# Àkíyèsí Àwọn Ẹ̀tọ́ Òsìṣẹ́
# Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti ÀÀBÒ tí a Kò Lò:

Tí o bá sisẹ́ fún abala àkoko nibi isẹ́ kan, tabi ilé-iṣẹ́ ti kì í se lati jèrè ni NYC tàbí tí o bá nsisẹ ninu ilé kan ni NYC gẹgẹ bí osisẹ abẹlé, o ni ẹtọ́ si àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò lati setọju ara rẹ tabi ẹnikẹni tí o jẹ́ mọlẹbi rẹ. O ni ẹtọ yi ipòkipò yòówù kí ipò isilọ-si-ilu-mìí rẹ jẹ́. Agbanisisẹ rẹ gbọdọ fún ọ ní akiyesi yi to nsàlàyé awọn ẹtọ rẹ.

## Iye Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti Ààbò:

- Agbanisíṣẹ́ rẹ gbọ́dọ̀ pèsè ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí ó tó ogójì wákàtí ní gbogbo ọdún.

**Bẹrẹ lati Ọjọ Kínní Osù Kinni Ọdún 2021:**

- Agbanisíṣẹ́ pẹlu 100 tabi awọn oṣiṣẹ diẹ sii rẹ gbọ́dọ̀ pèsè ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí ó tó wákàtí mẹrindinlọgọta ní gbogbo ọdún.

Ọdún kàlẹ́ndà ti agbanisíṣẹ́ rẹ ____________________ jẹ́: ____________________
Osù Kini / Osù tó kẹhin

O n gba ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo ti wákàtí kan fún gbogbo wákatí ọgbọn tí o fi sisẹ́, tí ó tó àpọ̀jù wákàtí ogoju ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo láàrín ọdún kan.

**O ní ẹ̀tọ́ láti bọ́ lọ́wọ́ ẹ̀san LÁTI ọwọ́ agbanisíṣẹ́ rẹ fún lílo ìgbà ìsinmi àìsàn ÀTÌ ÀÀBÒ.**

- Agbanisisẹ rẹ ni awọn osisẹ márùún tabi jubẹlọ.
- Agbanisisẹ rẹ ni awọn osisẹ ti kò tó márùún Sugbọn ti àkópọ̀ owo tó nwọle jémiliọnù kan dọlà tàbí jubẹlọ.
  Bẹrẹ lati Ọjọ Kínní Osù Kinni Ọdún 2021.
- O nsisẹ ninu ile ẹnikan gẹgẹ bí osisẹ abẹle; fún àpẹrẹ olutọju ọmọ, olutọju ilé, tabi osisẹ amúgbálẹgbẹ.
  *Àkíyèsí:* Òfin náà dáàbòbo osiṣẹ abẹle kan tàbi jubẹlọ nínú ilé kan.

**O ní ẹ̀tọ́ láti bọ́ lọ́wọ́ ẹ̀san LÁTI ọwọ́ agbanisíṣẹ́ rẹ fún lílo ìgbà ìsinmi àìsàn ÀTÌ ÀÀBÒ.**

- Agbanisisẹ rẹ ni awọn oṣiṣẹ ti o din márùún ti akopọ owó tó nwọle din ni mílíọnù kan dọlà.

Èyítí ó tó ogójì wákàtí ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbò tí a kò lò ni o le sún sí ọdún tí ń bọ̀.

## Iye Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti Ààbò:

- Lò ó fún ìlera rẹ, ati lati gba ìtọ́jú isègùn tàbi fún ìwòsàn kúrò nínú àìsàn tabi ifarapa.
- Lò ó lati sètọju mọlẹbi kan ti ó nsaisan ti ó sí níláti lọ sílé ìwòsàn.
- Lò ó nigbati isẹ rẹ tàbí ilé ìwé ọmọ rẹ bá tilẹkun pàjáwiri nitori ìlera ará ìlú.
- Lò ó fún ààbò rẹ tabi ààbò mọlẹbi kan nitori iwa-ipá abẹle, ifọwọpanilara ti ó kò fẹ́ fún ìbálòpọ̀, àyọjúràn, tabi ififipá tani sókè òkun.

Agbanisisẹ rẹ lè fẹ ki o se ifiransẹ akiyesi sáájú lilo àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò; fún àpẹẹrẹ lati rí onísègùn tàbi lati lọ fún igbẹ́jọ́ ilé-ẹjọ́. O kò níláti se ifiransẹ akiyesi sáájú ní ti lilo àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò lairotẹlẹ; fún àpẹẹrẹ àìsàn òjiji tàbí isegun pàjáwiri.

O ní ẹ̀tọ́ láti sọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ. O kò níláti sàlàyé lẹkunrẹrẹ fún agbanisisẹ rẹ ìdí tí o fi lo àkókò ìsimi ìgbà àìsàn tàbi ààbò.

Agbanisíṣẹ́ rẹ nílò ìwé àkọsílẹ̀ ti o bá lò ju ọjọ́ mẹ́ta ti ìgbà ìsinmi àìsàn àti ààbo lọ nígbà kannáà. Agbanisisẹ rẹ gbọdọ san pada gbogbo owó tí o ba lo fún àwọn ìwé àkọsílẹ tó yẹ. Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àsírí isegun rẹ tàbí ipo ti ará rẹ kò gbọ̀dọ̀ wà nínú àkọsílẹ.

## Ìgbà Ìsinmi Àìsàn àti ÀÀBÒ tí a Kò Lò:

Agbanisiṣẹ rẹ gbọdọ:

- Fún ọ ní àkọsílẹ̀ ilana àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò ti ó sàlàyé bí o se le lo awọn anfaani rẹ.
- Sọ fún ọ iye àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò ti o ti lo, àti èyí tí ó kù ní àkókò ìdánwò kọọkan.

## Kò sí Ìgbẹ̀san:

Ó lòdì sí òfin láti fiyajẹ tàbi sèdádúró lẹ́nu isẹ awọn osisẹ nitori pe wọn bèrè fún, tàbi wọn nlo àkókò ìsimi ìgbà àìsàn àti ààbò tabi fún irohin titàpá sí òfin.

NYC Consumer and Worker Protection

**Kàn si Ìdáàbòbò Olùrajà ati Osisẹ lati kọ́ sì tabi lati kọ'we ẹ̀sùn.**

Ìgbà **nyc.gov/workers** Ìsinmi **311** Àìsàn àti ÀÀBÒ tí a Kò Lò.

O si tún lè se ìtanilólobó ÀÌLÓRÚKỌ.

12/31/2020